*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbiyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# YAN ÌYÈ

**(Jòhánù 3:16)**

Ọlọ́run dá gbogbo wa ní àwòrán ara Rẹ̀ (Gẹ́nẹ́sísì 1:27). Ó tún fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó wù wá. Aà bá ti ní láti nífẹ̀ẹ́ Rẹ̀ bí ó ti wù ú, kí a sì ṣègbọràn sí i bí ó ti wù ú, bí Ó bá ti dá wa gẹ́gẹ́ bíi rọ́bọ́ọ̀tì; ṣùgbọ́n èro Rẹ̀ ní àkókò ìṣẹ̀dá kì í ṣe láti fi ipá mú wa (àwa tí Ó fẹ́ràn jùlọ nínú gbogbo ohun tí Ó dá) kí a ṣe ohun tí yóò lòdì sí ìfẹ́ ọkàn tiwa. Ọlọ́run fẹ́ kí gbogbo wa fi ìfẹ́ hàn án ní òtítọ́ àti ní odòdò, láti inú ọkàn wa. Ó sì wù ú kí a tẹ́ríba fún un nítorí a yàn láti ṣe bẹ́ẹ̀, dípò kí a ṣé gẹ́gẹ́ bíi ọ̀ran ti ipá.

Ọlọ́run fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó wù wá, ṣùgbọ́n Ó tún kìlọ̀ fún wa nípa àbájáde ẹ̀ṣẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ti kìlọ̀ fún Ádámù àti Éfà nígbà tí Ó sọ fún wọn pé kí wọ́n má ṣe jẹ nínú Igi Ìmọ̀ Rere àti Búburú (Gẹ́nẹ́sísì 2:16-17) Jẹ́ ká ṣàyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn àbájáde Ẹ̀bùn Òmìnira tí Ó fún wa yì í:

***Ṣé ó ṣeé ṣe kí Ọlọ́run jẹ́ kí ènìyàn ṣe ohun tí ó bá fẹ́, bó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀ṣẹ̀ ni?***

Bẹ́ẹ̀ni. Rántí pé Olóore-ọ̀fẹ́ ni Ọlọ́run. Ó sì ti fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó bá wù wá.

***Ǹjẹ́ Ọlọ́run lè dá ènìyàn dúró láti máa dẹ́ṣẹ̀?***

Bẹ́ẹ̀ni. Ọlọ́run lè dá ènìyàn dúró, nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ẹni náà. Èyí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìdí tí ó ṣe pàtàkì kí o gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún wa nípasẹ̀ Krístì. Tí o bá gbà á,



Ẹ̀mí Mímọ́ yóò wá gbé nínú rẹ. Ìwọ kò ní agbára láti yẹra fún ẹ̀ṣẹ̀ láìsí Ẹ̀mí Mímọ́. Àwọn tí wọ́n wà nínú Krístì máa ń dẹ́ṣẹ̀ nígbà mìíràn tí wọ́n bá yàn láti tẹ̀lé ọ̀na tiwọn; ṣùgbọ́n Ọlọ́run máa ń dárí jì wọ́n tí wọ́n bá ti jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọn fún un, tí wọ́n sì gbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ́ láti yí padà. Ọlọ́run ń dárí jì wọ́n nítorí pé Ó jẹ́ Ọlọ́rọ̀ ní àánú, àti pé, wọ́n ní òdodo Jésù Krístì. Síwájú sí i, Ọlọ́run máa ń tọ́ àwọn tí ó ti gba Krístì sí ọ̀nà tí ó yẹ, tí wọ́n bá ń dẹ́ṣẹ̀ lọ. Ó ń bá wọn wí lọ́nà tí ó wù ú, gẹ́gẹ́ bíi Bàbá sí ọmọ, kí wọ́n lè dúró ṣinṣin, kí wọ́n má sì bára wọn ní ọ̀run àpáàdì nígbẹ̀yìn (Hébérù 12:6). Ènìyàn tí ó kọ̀ láti gba Krístì kò ní àwọn àǹfààní wọ̀nyí.

***Kíni yóò ṣẹlẹ̀ tí ènìyàn bá dẹ́ṣẹ̀, tí ó sì ti kọ̀ láti gba ìdáríjì, nípa kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà?***

Bíbélì sọ wípé Ikú ni èrè ẹ̀ṣẹ̀, ṣùgbọ́n Ìyè Àìnípẹ̀kun ni Ẹ̀bùn Ọlọ́run nínú



*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbiyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



YAN ÌYÈ

(Jòhánù 3:16)

Ọlọ́run dá gbogbo wa ní àwòrán ara Rẹ̀ (Gẹ́nẹ́sísì 1:27). Ó tún fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó wù wá. Aà bá ti ní láti nífẹ̀ẹ́ Rẹ̀ bí ó ti wù ú, kí a sì ṣègbọràn sí i bí ó ti wù ú, bí Ó bá ti dá wa gẹ́gẹ́ bíi rọ́bọ́ọ̀tì; ṣùgbọ́n èro Rẹ̀ ní àkókò ìṣẹ̀dá kì í ṣe láti fi ipá mú wa (àwa tí Ó fẹ́ràn jùlọ nínú gbogbo ohun tí Ó dá) kí a ṣe ohun tí yóò lòdì sí ìfẹ́ ọkàn tiwa. Ọlọ́run fẹ́ kí gbogbo wa fi ìfẹ́ hàn án ní òtítọ́ àti ní odòdò, láti inú ọkàn wa. Ó sì wù ú kí a tẹ́ríba fún un nítorí a yàn láti ṣe bẹ́ẹ̀, dípò kí a ṣé gẹ́gẹ́ bíi ọ̀ran ti ipá.

Ọlọ́run fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó wù wá, ṣùgbọ́n Ó tún kìlọ̀ fún wa nípa àbájáde ẹ̀ṣẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ti kìlọ̀ fún Ádámù àti Éfà nígbà tí Ó sọ fún wọn pé kí wọ́n má ṣe jẹ nínú Igi Ìmọ̀ Rere àti Búburú (Gẹ́nẹ́sísì 2:16-17) Jẹ́ ká ṣàyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn àbájáde Ẹ̀bùn Òmìnira tí Ó fún wa yì í:

Ṣé ó ṣeé ṣe kí Ọlọ́run jẹ́ kí ènìyàn ṣe ohun tí ó bá fẹ́, bó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀ṣẹ̀ ni?

Bẹ́ẹ̀ni. Rántí pé Olóore-ọ̀fẹ́ ni Ọlọ́run. Ó sì ti fún wa ní òmìnira láti ṣe ohun tí ó bá wù wá.

Ǹjẹ́ Ọlọ́run lè dá ènìyàn dúró láti máa dẹ́ṣẹ̀?

Bẹ́ẹ̀ni. Ọlọ́run lè dá ènìyàn dúró, nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ẹni náà. Èyí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìdí tí ó ṣe pàtàkì kí o gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún wa nípasẹ̀ Krístì. Tí o bá gbà á,

2

Ẹ̀mí Mímọ́ yóò wá gbé nínú rẹ. Ìwọ kò ní agbára láti yẹra fún ẹ̀ṣẹ̀ láìsí Ẹ̀mí Mímọ́. Àwọn tí wọ́n wà nínú Krístì máa ń dẹ́ṣẹ̀ nígbà mìíràn tí wọ́n bá yàn láti tẹ̀lé ọ̀na tiwọn; ṣùgbọ́n Ọlọ́run máa ń dárí jì wọ́n tí wọ́n bá ti jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọn fún un, tí wọ́n sì gbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ́ láti yí padà. Ọlọ́run ń dárí jì wọ́n nítorí pé Ó jẹ́ Ọlọ́rọ̀ ní àánú, àti pé, wọ́n ní òdodo Jésù Krístì. Síwájú sí i, Ọlọ́run máa ń tọ́ àwọn tí ó ti gba Krístì sí ọ̀nà tí ó yẹ, tí wọ́n bá ń dẹ́ṣẹ̀ lọ. Ó ń bá wọn wí lọ́nà tí ó wù ú, gẹ́gẹ́ bíi Bàbá sí ọmọ, kí wọ́n lè dúró ṣinṣin, kí wọ́n má sì bára wọn ní ọ̀run àpáàdì nígbẹ̀yìn (Hébérù 12:6). Ènìyàn tí ó kọ̀ láti gba Krístì kò ní àwọn àǹfààní wọ̀nyí.

Kíni yóò ṣẹlẹ̀ tí ènìyàn bá dẹ́ṣẹ̀, tí ó sì ti kọ̀ láti gba ìdáríjì, nípa kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà?

Bíbélì sọ wípé Ikú ni èrè ẹ̀ṣẹ̀, ṣùgbọ́n Ìyè Àìnípẹ̀kun ni Ẹ̀bùn Ọlọ́run nínú

3

Jésù Krístì, Olúwa wa (Róòmù 6:23). Kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà, kí o lè gba ìdáríjì fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ìkésíni Sátánì sí ọ láti wà nínú adágún iná pẹ̀lú rẹ̀, títí aiyéraiyé.

***Kíni ìdí tí ó fi léwu fún ènìyàn láti máa gbé ìgbésí aiyé lọ, láì jọ̀wọ́ rẹ̀ fún Jésù Krístì?***

Yàtọ̀ sí òtítọ́ pé Jésù Krístì ń bọ̀ padà wá láìpẹ́, lójijì (1 Tẹsalóníkà 5:2-3), a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni (Jákọ́bù 4:13-15). Ọlọ́run lè pe ẹnikẹ́ni padà nígbàkugbà, ìdájọ́ ló sì kàn lẹ́yìn ikú. Ó ṣeni láàánú pé kò sí àyè mọ́ láti ní ìgbàlà lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ yóò wá bá ara wọn ní ọ̀run àpáàdì, nígbẹ̀yìn. Ọ̀pọ̀ ìtọ́kasí ló wà nínú Bíbélì nípa ọ̀run àpáàdì. Àwọn tó yẹ ká ronú lé lórí jùlọ ni àwọn tó fi yé wa pé, ibi ìdálóró tí ẹ̀dá kankan kò ní lè fara dà ni. Ibi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà títí



láí (Máàkù 9:43-48)! Ọ̀run àpáàdì kìí ṣe ibi tó rọrùn rárá fún ẹnikẹ́ni láti wà títí aiyéraiyé. Ààìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o yàn láti má ṣe ohun tí ó yẹ, kí o lè yè bọ́ ibi oró tí à ń sọ yìí. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti gba Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kun tí Ọlọ́run fi ìfẹ́ fún gbogbo wa (Jòhánù 3:16). Yan Ìyè, nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì lónìí!

**Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?**

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.



3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*



Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

**Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!



Jésù Krístì, Olúwa wa (Róòmù 6:23). Kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà, kí o lè gba ìdáríjì fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ìkésíni Sátánì sí ọ láti wà nínú adágún iná pẹ̀lú rẹ̀, títí aiyéraiyé.

***Kíni ìdí tí ó fi léwu fún ènìyàn láti máa gbé ìgbésí aiyé lọ, láì jọ̀wọ́ rẹ̀ fún Jésù Krístì?***

Yàtọ̀ sí òtítọ́ pé Jésù Krístì ń bọ̀ padà wá láìpẹ́, lójijì (1 Tẹsalóníkà 5:2-3), a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni (Jákọ́bù 4:13-15). Ọlọ́run lè pe ẹnikẹ́ni padà nígbàkugbà, ìdájọ́ ló sì kàn lẹ́yìn ikú. Ó ṣeni láàánú pé kò sí àyè mọ́ láti ní ìgbàlà lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ yóò wá bá ara wọn ní ọ̀run àpáàdì, nígbẹ̀yìn. Ọ̀pọ̀ ìtọ́kasí ló wà nínú Bíbélì nípa ọ̀run àpáàdì. Àwọn tó yẹ ká ronú lé lórí jùlọ ni àwọn tó fi yé wa pé, ibi ìdálóró tí ẹ̀dá kankan kò ní lè fara dà ni. Ibi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà títí

4

láí (Máàkù 9:43-48)! Ọ̀run àpáàdì kìí ṣe ibi tó rọrùn rárá fún ẹnikẹ́ni láti wà títí aiyéraiyé. Ààìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o yàn láti má ṣe ohun tí ó yẹ, kí o lè yè bọ́ ibi oró tí à ń sọ yìí. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti gba Ẹ̀bùn Ìyè Àìnípẹ̀kun tí Ọlọ́run fi ìfẹ́ fún gbogbo wa (Jòhánù 3:16). Yan Ìyè, nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì lónìí!

**Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?**

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

5

3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*

6

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

**Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?**

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

7